## ESI IWADI NI RANPE

Esi iwadi iwuwasi si ilera larin awon omo ile iwe (HBSC) ni ori'le ede Ireland ti odun 2010 ni ranpe ni a ko si isale yii:

### Ilera gbogbo ara

Lakopo, iye awon omo ti o so wipe ilera awon dara lopo je ipin lona ogorun metalelogbon (33%), awon ti inu won dun gidigidi, ipin lona ogorun aadota (50%) ati awon ti won ni itelorun gidigidi pelu igbesi aye won, ipin lona ogorun merindinlogorin (76%) si wa bose ri ni odun 2006. Owopo larin awon omo kekeke ati awon omodekunrin lati rohin pe ilera awon dara. Osi wopo larin awon omode ti won wa lati idile tabi egbe awujo irele lati rohin pe awon ni'telorun gidigidi pelu igbesi aye won.

Osuwon awon omo ti won wa lati egbe awujo keta ati ikerin ti won so pe ilera awon dara pupo je ipin lona ogorun mokandinlogoji (39%), inu didun gidigidi na si je bi ipin lona ogorun aadorin (70%) si be bo se wa ni odun 2006. Ko si iyato to ni apeere larin egbe awujo tabi eya lokunrin tabi lobirin.

### Ogun lile lilo

Lapapo, a ri wipe idinku wa ninu esi ti odun 2010 si ti odun 2006 ninu awon esi ti a gba nipa ewe, oti ati ogun oloro lilo larin awon omo ile iwe ori'le ede Ireland.

### Siga mimu

Awon esi siga mimu ti aipe yii je ipin lona ogorun mejila (12%) ati wipe mimu siga rara ti o je ipin lona ogorun meatdinlogbon (27%) ti posi si ti odun 2006 ti o je ipin lona ogorun meedogun (15%) ati siga mimu, ipin lona ogorun merindinlogoji (36%). A ri wipe iyato ti owa nipa ti ojo ori ati egbe awujo je nkan pataki fun iwon siga mimu mejeji, awon omo ti o ti dagba ati awon ti o wa lati egbe awujo irele le rohin siga mimu daradara ju awon to ku lo. Awon omodekunrin le rohin iru awon iwa yi ju awon omodebirin lo. Ko si iyato ti o ni apeere lara ikan s'ikan ninu awon omo egbe awujo ti a pin kale fun iwadi na.

## Oti mimu

Esi nipa oti mimu ti dinku larin awon omo ile iwe ni ori'le ede Ireland lati odun 2006 pelu ipin lona ogorun merindinlaadota (46%), awon omo ti o so wipe awon ti muti ri (ipin lona ogorun metalelaadota (53%) ni o so wipe awon mu oti ri ni odun 2006). Osuwon oti amupara (ipin lona ogorun mejidinlogbon-28% ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun mejilelogbon-32% ni odun 2006) ati irohin mimu oti para ni ogbon ojo seyin (ipin lona ogorun mejidinlogun (18%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun ogun (20%) ni odun 2006) na ti dinku. Iyato larin ojo ori ati eya lokunrin tabi lobirin ni a sakiyesi fun gbogbo awon iwon oti mimu mererin ti a se, awon omode ti o ti dagba ati awon omokunrin le rohun oti mimu ati amupara ju awon y'oku lo. Awon omode ti won wa lati egbe awujo irele seese ki won rohin wipe awon ti mu oti yo gidigidi ri.

## Ogun oloro lilo

Irohin igbo lilo ni osu mejila sehin (ipin lona ogorun mejo (8%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun merindinlogun (16%) ni odun 2006) ati ogbon ojo sehin (ipin lona ogorun marun (5%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun meje (7%) ni odun 2006) ti dinku. Awon omodekunrin ati awon omo ti o ti dagba seese ki won rohin igbo mimu ju awon y'oku lo. Ko si iyato ti o ni apeere larin awon omo egbe l'awujo.

## Ounje ati iwuwasi si aijeun

Ounje (fun apeere, efo) ati iwuwasi si ilera eni nipa ounje (fun apeere, aijeun lati din iwon ara eni ku) larin awon omo ile iwe ni ori'le ede Ireland ti san tabi duro sinsin fun iwadi ti a se ni odun 2006.

## Ounje jije

Lapapo, ipin lona ogorun ogun (20%) awon omo lo rohin wipe awon ma n je eso ju eekan lojumo lo (ipin lona ogorun mokandinlogun (19%) ni odun 2010) ati ipin lona ogorun ogun (20%) rohin wipe awon ma n je efo ju eekan lojumo lo (ipin lona ogorun mejidinlogun (18%) ni odun 2006). Awon omobirin, awon omo kekeke ati awon ti won wa lati egbe awujo oke le rohin efo ati eso jije ju awon omo y'oku lo. Osuwon awon omo ti o rohin nkan didun (suuti) mimu, jije lojojumo tabi loorekoore lapapo (ipin lona ogorun metadinlogoji (37%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun mokandinlogoji (39%) ni odun 2006) ati awon ti won rohin oti didun

mimu lojojumo tabi loorekoore (ipin lona ogorun mokanlelogun (21%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun merindinlogbon (26%) ni odun 2006) ti dinku lati odun 2006. Awon omo ti o dagba ati awon omo ti o wa lati egbe awujo irele seese ki won rohin suuti ati oti aladun mimu deede. Iyato laarin eya lokunrin tabi lobirin na wa lara awon nkan ti a sakiyesi, asi ri wipe awon omodebirin seese ki won rohin nkan adidun (suuti) jije leralera (ipin lona ogorun mokondinlogoji (39%) omodebirin ati ipin lona ogorun merinlelogbon (34%) omodekunrin) ati wipe awom omodekunrin seese ki won rohin oti aladun mimu leralera (ipin lona ogorun metalelogun (23%) omodekunrin ati ipin lona ogorun mokandinlogun (19%) omodebirin).

Ari awon awose irukanna pelu eri laarin awon omo egbe awujo keta ati ikerin, pelu piposi ninu efo jije (ipin lona ogorun merindinlogbon (26%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun mokanlelogun (21%) ni odun 2006), kosi iyato ninu eso jije (ipin lona ogorun ogbo -30%) tabi suuti mimu (ipin lona ogorun meedogun (15%) ni odun 2010 ati ipin lona ogorun mejidinlogun (18%) ni odun 2006).

## Iwuwasi si ounje

Irohin aijeun aaro ni oseese ki oti yipada lati odun 2006 (ipin lona ogorun metala (13%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun merinla (14%) ni odun 2006). Oseese ki awon omodebirin, awon omo ti o ti dagba ati awon omo ti won wa lati egbe awujo irele na rohin wipe awon ki'jeun aaro ni ojojo ose. Osuwon awon omo egbe awujo keta ati ikerin ti o rohin aijeun ni ojojo ose na si duro sinsin sibe lati odun 2006 (ipin lona ogorun meji-2%).

A bi awon omode nipa bi won se ma n lo ile iwe tabi ori ibusun lebi si nitoripe kosi ounje toto ninu ile. Lapapo awon omo ipin lona ogorun mokanlelogun (21%) lo rohin wipe awon lo si ile iwe tabi ori ibusun lebi, eyi kosi ju ti odun 2006 lo (ipin lona ogorun metadinlogun-17%). Awon omodekunrin, awon omo kekeke ati awon omo ti o wa lati egbe awujo irele le rohin lilo ile iwe tabi ibusun lebi ju awon to ku lo.

Irohin nipa isera eni fun ounje (tabi sise nkan miran) lati din iwon ara eni ku ni odun 2010 (ipin lona ogorun metala-13%) duro sinsin sibe lati odun 2006 (ipin

lona ogorun mejila (12%). Awon omodebirin ati awon omo to ti dagba le rohin isera eni fun ounje (tabi gbigba iyanju) lati din iwon ara won ku.

## Ere idaraya ati aapon agbara

Iyato die ni oti wa ninu sise ere idaraya, apon agbara ati aise rara ni iwadi HBSC odun 2010. Lapapo ipin lona ogorun mokanlelaadota (51%) awon omo lo rohin wipe awon ma n se ere idaraya leemerin tabi ju be lo lose (ipin lona ogorun metalelaadota-53% ni odun 2006), ipin lona ogorun mesan (9%) awon omo lo rohin wipe awon ma n darapo mo sise ere idaraya to lagbara leekankan losu (ipin lona ogorun mewa (10%) ni odun 2006) ati ipin lona ogorun meedogbon (25%) awon omo lo rohin wipe awon ni apon agbara toto ni gbogbo ojo ose (ipin lona ogorun metadinlogbon (27%) ni odun 2006). Pelu awon osuwon meteta yii, eya lokunrin tabi lobirin ati iyato ninu ojo ori yo pelu eri to daju. Lakotan, awon omokunrin ati awon omo ti ko dagba pupo le rohin nini apon ju awon y'oku lo. Awon omo ti o wa lati egbe awujo irele seese ki won rohin aini apon tabi agbara, awon omo ti o wa lati egbe awujo aarin na si le royin nini aapon agbara ni gbogbo ojo ose ju awon toku lo.

Larin awon omo egbe awujo keta ati ikerin, ipin lona ogorun aadorin (70%) omo lo rohin sise ere idaraya l'emerin tabi jube lo laarin ose (ipin lona ogorun mejilelaadorin (72%) ni odun 2006), ipin lona ogorun meje (7%) rohin didarapo mo sise ere idaraya to logbara lekankan losu (ipin lona ogorun mejo (8%) ni odun 2006).

## Itoju ara eni

Titoju ara eni nipa fifo eyin ni iye igba to ju ekan lojumo lo (ipin lona ogorun metadinlaadorin (67%), duro sinsin sibe lati odun 2006 (ipin lona ogorun metalelogota-63%), eyi na si wopo laarin awon omo ti won wa lati egbe awujo keta ati ikerin (ipin lona ogorun merindinlaadorin (66%) ni odun 2010 dipo ipin lona ogorun merinlelogota (64%) ni odun 2006). Awon omodebirin ti egbe awujo oke le rohin fifo eyin ju ekan lojumo ju awon omo toku lo. Ko si iyato to lapeere larin ojo ori awon omo na.

Abi awon omode na ni ibeeree bi won se ma n lo igbaja ijoko oko si. Lapapo, awon omo ti o to ipin lona ogorun mokanlelogorin (81%) lo rohin wipe awon ma n lo

igbaja ijoko oko, eyi duro sibe ti a ba fi we esi ti odun 2006 (ipin lona ogorun mokandinlogorin-79%). Awon omodebirin ati awon omo ti won ko dagba lopo le rohin lilo igbaja ijoko oko ju awon y'oku lo.

### Ifarapa

Iye awon omo ti o farapa ti o si nilo itoju ile iwosan leekan tabi jube ni osu mejila seyin lapapo ni odun 2010 (ipin lona ogorun metadinlogoji-37%) dinku si ti odun 2006 (ipin lona ogorun metalelogoji-43%) lo. Awon omodekunrin ati awon omo ti o dagba le rohin fifarapa daradara. Lara awon to rohin fifarapa, metadinlogota (57%) rohin wipe awon kole se nkankan fun bii ojo meta tabi ju be nitori ifarapa yii (ipin lona ogorun merindinlogota (56%) ni odun 2006). Eya okunrin tabi obirin pelu iyato ninu ojo ori farasin awon irohin ti o jade nipa bi ifarapa se po si, ko si si ipa kankan ti ari ti o ko lori awon egbe awujo.

### Ipata sise

Osuwon awon omo ti o rohin wipe awon omo miran ti yo awon lenu ri ko yipada lati odun 2006 ti o je ipin lona ogorun merinlelogun (24%). Sibesibe, osuwon awon omo ti o rohin yiyo awon omo miran lenu ni osu meji sehin ti dinku (ipin lona ogorun metadinlogun (17%) ni 2010 dipo ipin lona ogorun mejilelogun (22%) ni odun 2006). Awon omodekunrin le rohin yiyo awon omo miran lenu ati pe awon na ma n yo awon omo miran lenu. Awon omo ti ko tii dagba seese ki won rohin wipe awon omo miran ti yo awon lenu ri, awon omo ti o ti dagba si le rohin yiyo awon omo miran lenu. Ko si iyato larin awon egbe awujo.

Ipin lona ogorun awon omo egbe awujo keta ati ikerin ti won rohin wipe awon omo miran ti yo awon lenu (ipin lona ogorun metadinlogoji-37%) wa sibe, ko yi pada si ti odun 2006. Ko si si iyato ti o lapeere larin eya lokunrin ati lobirin tabi awon egbe awujo.

### Iwuwasi si ibalopo

Lapapo, ipin lona ogorun metadinlogbon (27%) lara awon omo ti ojo ori won wa laarin meedogun (15) ati metadinlogun (17) rohin wipe awon ti ni ibalapo ri. Awon omodekunrin ati awon ti o wa lati egbe awujo irele le rohin nini ibalopo ri ju awon y'oku lo.

Lara awon ti o rohin nini ibalopo ri, ipin lona ogorun metalelogorun (93%) rohin lilo roba idabobo nigba ti won ni ibalopo kehin ati wipe ipin lona ogorun mokandinlogota (59%) lo rohin wipe awon ti lo ogun ifeto s'omo bibi ri. Awon omodebirin le rohin lilo ogun ifeto somo bibi lati dena oyun nini, ko si si iyato larin eya lokunrin tabi lobirin ninu irohin roba idabobo lilo gege bi adena oyun nini. Kosi iyato na larin egbe awujo.

**Translated by Damilola Awobiyi**